**Ikede**
A fi eyi kede fun enyin Okawe wa Asoju Iwe wa wipe ki e tete ma fi owo ranse siwa nitoripe ohun elo iwe irohin ti gb'owo le'ri. Bi beko, ao da wo oluware duro, ao si gba owo wa lowo re.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

LADIES BRASSIERES
2/-6d, 3/- 4/-6d
& 5/-6d each.
Obtainable at:-
A. B. AKINYEMI
10A, Moloney Bridge Street
LAGOS.

VOL. VII No. 437 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA OCTOBER 15, 1955 IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2)

## OLOYE ASAJON-OLOJA EREKO SE AJODUN KERIN



Awon enia pataki-pataki ati awon Oloye, awon omo'ba, awon Kansilo ilu, awon olowo ati awon borokini enia l'o peju-pese sibi Ajodun ti omo'ba olola Aminu Kosoko ti ise Oloye Asajon Oloja Ereko se fun ti odun kerin ti o ti g'ori oye re na.

Omo'ba Olola Aminu Kosoko se ajodun na ni ojo Eti ti ise ojo keje osu yi ni Agbo'le re ni 32, Kosoko Street, l'Eko. Oloye Asajon se nkan pataki ni ojo na, eyiti yio je iranti aiyeraiye fun gbogbo enia, iyen ni Ilewe awon omode ti o si ni Agbala re fun eye ajodun na.

Ilu Gbedu ati orisirisi ilu ni nwon njo bi kokoro, oloye Asajon fi onje ati orisiri oti te gbogbo enia lorun, jowo enikeji nigbati onje adidun ati oti atata po tan, oku adie ko mo eniti o tu ni oro da fun awon to mo nkan mu.

Irohin ko to afojuba ni eye ajodun na lati owuro titi ile fi su.

Asese tun se,
Oloye wa se'yi na o,
Yio se 'miran si.

Ade a pe lori, Bata a pe l'ese, Abere a d'owa o, Oloye Asajon ti wa. Oloja Ereko.

**THE NATIONAL BANK**

**OF NIGERIA LIMITED**

Ona tara ti enia legba lati di onisowo nile Nigeria wa ni ile ifiowopamosi ti NATIONAL BANK
Enikeni ti o ba fe kan ogunlogo aimoye awon onisowo ile Nigeria lara, yala lati ma ta oja fun won ni, tabi lati ma ra awon ohun ogbin ile wa ki o lo si NATIONAL BANK

ILE ISE WA NI EKO:-

37, MARINA, P. O. BOX 508, LAGOS

WON ASOJU WA NILU OB NIYI
THE NATIONAL PROVINCIAL BANK
(Overseas Branch)
1. PRINCESS STREET LONDON E. C. 2.
THE COMPTOIR NATIONAL DESCOMPTE DE PARIS
8/13, KING WILLIAMS STREET, LONDON E. C. 4.

## Njemanze Di Ige Adubi Ari Ero Barin.

Nigbati Adajo John Bennet bere si se alaye ejo ti awon odaran ti nwon mu fun esun apania 'ori iku Akorin Olohun'yo Israel Njemanze ati ejo ti awon odaran enia na ro lati fi ja ajabo ninu esun na, fun awon Agbagba mejila ti nwon yio se asaro lori ejo na, o gba Adajo to wakati mejo gbako ki o to pari alaye re. O bere oro ni dede agogo mesan owuro, o si pari oro re ni agogo marun irole.

Lehinti Adajo se alaye na tan ni ojo Tuesday ti ise ojo kokanla osu yi, ni awon Agbagba mejila (Jury) wo iyara ... O gba won ni ... meji ki nwon o ... wa fi konk... jo lowo wipe ... ni, ikeji, eketa, ... run ati ek... odaran kefa ... ko jebi.

Awon Od... niwonyi:- P... gwu, Mich... o, Lawal Dada, D... olabi, Cyril Anikwe, ati Samuel Jegede Awon enia meji ti nwon da sile ni Lamidi Ayinde au Layi Adewole.

### IDAJO KOTU

Ki Adajo to se idajo le awon odaran eni na l'ori, o se abere lowo won bi nwon ba ni oro lati so.

Peter Nwangwu so wipe, emi ko jebi emi ko l'opa a, sugbon iwo gegebi olori, o le se ohunkohun to ba fe p lu mi, emu ni mo lo mu nibe.

Michael Adeyemo so wipe, mo ni ife ologbe na gegebi ara mi, nko si ni ibinu si i, emi ko lo pa a, ko si ohun to le mu mi pa Njemanze, on nikan soso ni ya re bi gegebi emi na, awon to paro yi mo mi mo ninu okan won.

Lawal Dada wipe, Emu ni ni mo lo mu ni No. 8, Adegbite Street, nko mo ologbe na ri, emi ko lo pa Njemanze.

Dada Owolabi wipe, emi ko jebi, emi ko lo pa ologbe na.

Cyril Anikwe wipe, emi
(Wo yoku 'oju Ewe Kejo)

(Wo yoku 'oju Ewe Kejo)

## Akorin Olohun'yo



**Isreal Njemanze**

## Oku Olomo Sin Sin Tun Sin,

ABIDJAN. Ogbeni Emanuel Alawo Ademoyejo, omo ilu Ilawo, se inawo oku iya re o fi'le ponti, o fi odede ro'ko, ohun jije ati mimu ni o fi te gbogbo ena l'orun.

Ogbeni Ladisi Onilu ati Oni Sekere ati Aro fi ilu da bira lojo na, bena si ni awon to mo ijo jo nran bi keke okun, fi gbogbo re ndun yungba.

Die ninu awon elabaseye ojo na ni awon Ogbeni Emanuel Alabi, John olatunde, Jacob Olawore, Joseph Alabi, Daniel Salako, James Bandele, Samuel Toki, John Genro ati Samuel Olawoye.

Awon janmo Musulumi ni Alhaji Oseni, Olorungb'ebe, Yusufu Olawoye, Salami Abegunrin, Yusufu Gebo, Yesufu Olaleke Raji, Shitu Ajao Oshogbo, Raji Mosebolatan, Shitu Gbaro.

A si ki Lawani Alawo ti ise aburo omo oloku ku inawo ojo na, ki Olorun jeki ebin iya dara o.

### MO B'OLOMO YO

Ni ojo Aiku ti ise ojo kerindinlogun osu tokoja ni Ogbeni Salawu Ayandokun ati iyawo re Salamotu Agbeke se ikomojade, Alufa Abudu Layi ni o se eto isomo l'oruko ni ona ti Musulumi. Won so omo ni Amina Ayanlere.

Baba omo na nowo bi eleda lojo na, enia po bi omi, gbogbo ena ni baba omo na fi onje ati orisirisi Oti pelu Siga te l'orun, awon egbe baba omo pe sibasiba sibi ikomo na.

Ki adaruko die ninu awon to wa ba baba omo na seye lojo na, awon egbe Oba-bi-Olorun-kosi, ti ise egbe baba omo, Ogbeni Raji Oyeleru ti ise Baba Egbe, Bello Adedokun, Giwa, Gbadamosi Toyese, Amodu Ayanwola, Tijani Olaniyi, Amusa Oyeleye, Lamidi Oyesola, Amusa Bode, Samuel Adeniyi, Amusa Olatayo, Raji Faniyi, Emanuel Adeniji, Alufa Kanpa, Salawu Oyewo, Alufa Dauda, Iyafin Aminatu Fariyike, Humuani Oyeronke, Silawu Titilola, Adiatu Adebisi ati opolopo enia ti ako le daruko tan.

Ki Olorun da omo na si o.

# Ejo Omo'ba Ademiluyi.

Omo'ba Ademiluyi ti ro ejo re pari lori esun metadinlogun ti nwon fi sun nipa ole, iyiwepada ati bebe, Ogbeni H. T. Domingo to ti nse akowe Omo'ba Ademiluyi ri ni o jeri gbehin.

Nigba pupo ni Adajo fi nse ikilo fun Ademiluyi wipe ki o ye fi ori se apere fun eleri re. Idajo l'oku.


# Dokita Fihan Wipe

## Ose Palmolive Le Jeki Oju Re Dara

LARIN OJO MERINLA



**Ara mi Jolo o tun Jide Nisisiyi ti mo tele ilana Palmolive**

Iba ohun ti iwe yio se niyi :-
1 Fi ose Palmolive we oju 2 Fi biho re pa oju fun iseju kan 3 Fi aso nu kuro se be nigba meta lojumo fun ojo merinla,




EPO ILE AFRIKA

NI A FI SE OSE YI

COLGATE PALMOLIVE SOAP

# Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si Nmu Ireti Wa Fun Opo Enia

LOSAN ATI LORU KO NJEKI EHIN ENIA BAJE

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol.

Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje t'osan t'oru.



Sodium N. Lauroyl, Sarcosinate

SAME FAMILIAR PACKAGE



*OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.*

A ti fi Ododo oro yi han ninu iwe ti awon Onisegun hin te, awon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyiti o dara fun ehin to baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo




Ko si egbogi ehin kan ti o dara bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje.

**O Dara T'osan T'oru Ko Njeki Ehin Enia Baje.**



## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS


# Afibi San Ore Fa [illegible]ra Re Si Ijogbon

Lati Qwo ESQ IKOYI

Awon Yoruba li o npowe bayi wipe "Enitia ba se lore ti ko dupe, o dabi igbati Olosa ko eru eni lo". Oro na dori ko dori, o dori Orisa Ogun nigbati onfe lo si ogun na ti awon ara Ekiti gbe wa Orunmila ko i nile ni akoko na, nigba na ni obinrin opo ti o mbe ninu ile Orunmila (Obinrin opo yi ni Iyawo Orunmila ti o mu fi ndele, eyiyi ni Onipupa Ayawo Ife) on ni o wa da Ifa fun Ogun ti o ri Oguda-se, o si bere si ki i bayi pe:-

Opo ile Orunmila lo difa fun Ogun. Ti o nlo si ogun Igbo, Akara Ogun gbo, o rubo, aja o setutu tan, o lo si ogun.

Nigbati Ogun d… ju ogun, o gun na le fun awon awon ara Ile-Ife, sugbon nigbati Ogun towo bo awon ota lara, nse ni o npa won nigba-nigba. Nigbati Ogun na yio fi pari, O isa ogun mu awon obinrin mokanlerugba l'eru, o si ko gbogbo won de ile-Ife.

Orisa ogun mu igba ninu awon obinrin ti o ko l'eru, o lo fifun Olofin, okan soso ti o ku, o dara o si ni ewa, ni Ogun fi se Iyawo fun ara re. Irohin tun de wipe, ogun tun dehin, o si tile wa le ju ti isiwaju lo. Afara ko si, Orisa ogun tun gba ona ogun jija lo, ki o to tun pada wa sile nigba keji. Olofin ti ranse lo mu obinrin kansoso ti Orisa ogun fi se iyawo lo si ile ob… ti on ti oyun ti ogun fi si ninu ki o to tun lo si ogun nigba keji.

Bi Orisa Ogun ti mbo wa sile nigba keji, irohin ti lo ko o loju ona ti okan-le-nirinwo eru ti o mu ni ogun ti o si nko bo wa sile. Inu Orisa Ogun baje gidigidi nigbati o gbo oro yi, O si wipe, bi on ti nlo yi gbogbo ile Olofin ni on yio parun.

O fa ida re yo, o si bere si pa gbogbo ilu kilu ti o ba kan loju ona run o npa won be gege titi o fi wa kan Ile-Ife. Sibe ko dawo duro, ko si mo wipe on ti de ilu Olofin Ile-Ife nibiti on papaa gbe ti jade lo nigbati o pa awon ara ile Ife ku ogbon mefa enia ibe ni obinrin Arugbo kan ti ko le salo wa fi ohun rara kigbe daro si Orisa Ogun wipe:-

Gbajure- e-e-e-e e-e-e-
Okunrin gogoro ti ngba ojuto jade.

Nigbati Orisa Ogun gbo iru igbe yi, o sunra ki, o wipe tabi on de ilu ibiti nwon gbe mo on (Ile-Ife) O si te Ida re bo ile nibiti o de lojo na. Enikeni ti o ba de oja Oba ni Ife titi di oni, yio ri Ida re ojo na nibiti o gbe te e bole si.

A gbo siwaju wipe awon enia ti Orisa Ogun pa ni Ile-Ife bere si rojo lorun wipe, ojo ti nwon nile aiye koiti pe ki Orisa Ogun to ran won lo si orun laise ati lairo. Nigbati iregbe awon enia na po, nwon ranse si Ogun ki o wa gbo oro kan ni orun.

Nigbati Ogun yio lo, o lo ye Ifa wo, iru oro wo ni nwon nfe ba on so l'orun. ati wipe bi on yio ba jare, Qrunmila gbe Iporun re, o jan a mole, o si ri Irete-Tura, o bere si ki odu Ifa na bayi wipe:-

Ikere lo nse aya Eku Irawe du-du-du ni aya Qfin.
Ikoko lo nse aya Omi. Eni ba mowo kan Ikere,
nwaja Eku. Eni ba mese le irawe ofin, nwaja
Qfin. Eni ba mese le ikoko, nwaja omi.
Qrunmila ni eniti o ba gbese le iyawo on ko mo
pe, on ti mese le ona orun.

Qrunmila so fun Orisa Ogun wipe awon kan urojo re ni orun wipe Ogun ni o pa won laise lairo, sugbon Ifa so wipe Orisa Ogun ko wule pa won lasan, bi kose wipe nwon ti gbese le iyawo Ogun. Nitorina Ifa kilo fun Orisa Ogun ki o mase lo, nitoripe bi o ba se on Qrunmila ni on se be si, on yio sa gudugudu meje.

# ELETI OFE

A-NIU-WON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28 Kakawa Street Lagos "ELETI-OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL VII NO. 437 LAGOS SATURDAY OCT. 15 1955.


## Egbe Omo Oduduwa D'osu O Le Kenka.

Ipade Egbe Omo Oduduwa ti nwon se l'osc to koja ni akoko n'ilu Ado Ekiti, ipade na si dun tobe ti o tun l'ariurin pelu.

Lati odun keio ti nwon ti da Egbe yi sile, orisirisi anfaani ti ko ti si ri ni ile Yoruba ni o f'arahan, paapaa, larin awon oba wa ti Egbe se okunfa isowopo won pelu awon enia won ni gbogbo ile yoruba.

Eyi je ise rere pataki fun gbogbo ilu ati oniruru ona ti Egbe naa se ise re fun ire ati ilosiwaju gbogbo ilu Yoruba, nitori pe bi ede-aiyede kan ba be sile nibikibi, Egbe ki i sinmi beni nwon ki i si baye lati nowo ara won sise atunse ki aiye wa le r'oju ki a si ni ifayabale.

Ogbeni wa, Baba Egbe Omo Oduduwa, Dokita Akinola Maja ati Oloye Obafemi Awolowo ti ise akowe egbe ni a fi iyin ogo Egbe na fun u, nipa wahala won l'ori ire wa, ti a si tun ri Alaiyeluwa Oba Akenzua II. ti ilu Ibini (Benin City) ti o wa si ipade ti ilu Ado Ekiti yi

Ko ni re yin o, enyin baba wa.

## Yokolu Iyawo Gbe Oko Sanle, Oko Yo Ike

**Agbesi-Olomu** Okunrin kan ti a npe ni Taiwo ara Eruwa ati Kehinde iyawo re ara Alagbado. Omo ibeji ni toko-taya, awon si fe ara won. Akobi omo won ko nse ibeji, eyokan ni awon bi. Sugbon omo keji ti won bi je ibeji, obinrin kan, okunrin meji, sugbon okan kabo ninu awon omo okunrin.

Nigba gbogbo ni awon toko-taya ma mba ara won ja latari wipe, Kehinde feran awon omo obinrin ju awon okunrin lo. Kehin papaa a si ma fi Taiwo oko re sun esun wipe, olgba pupo ni o ma ura ukan fun awon omo re okunrin yio si wipe ti awon obinrin di igba miran titi be ko ri ra mo.

Lojo kan ti o je ojo oja Alagbado Kehinde gbe omo re okunrin ti o nto lowo fun Aburo re o gbe ayi obinrin pon funra re, o ni on nlo si oja Alagbado. K pe pupo lehin ti Kehinde lo tan ni omo okunrin ti o gbe fun aburo re bere si ke, awon be e ki gba ni awo ba wa iyawo re Kehinde lo.

(Wo oju ewe keje)


## ABOKI



TI IWULO RE LOKIKI yika Nigeria

O'EMANI lo je fun ilekile Fun orisirisi AILERA, atata Gbogbonse lo je.

RA IGO KAN LONI nitori AFIBIDAN ni

LODO

IBUKUN-OLU MEDICINE STORES

Amunigun Street, Phone 189x, Box 295, Ibadan.

FUN RUN GEHIN-GEHIN


## Woli Egbe Kerubu Ati Serafu, Agbadura-Gba'yawo

**Irohin araku-yamu kan ti a gbo laipe yi ni wipe Woli egbe Kerubu ati Serafu kan, awon egbe aladura, ni o se adura fun iyawo omo egbe re titi ti Emi mimo fi se ise lara iyawo oni-yawo.**

**Bi oro na ti lo niyi:- A gbo wipe Woli kan wa ti o ko awon enia jo wipe on ngba adura se, o si je Woli pataki fun awon Ijo Kerubu ati Serafu o wa sofun iyawo odomokunrin kan ti ise okan ninu awon egbe Kerubu ati Serafu ti woli agbadurase elenmo yi, wipe ki o ma wa fun akanse adura ki Olorun le fi omo ta l'ore ati pe ki ohun gbogbo le to won, toko-taya si gba be.**

**Iyawo si bere si lo fun akanse adura l'odo Woli agbadura-gbayawo yi, o si sofun iyawo wipe bi awon ba ti bere si gba adura, ki iyawo ma a wipe amin, amin, bi kokoro kan ba nrin o nidi, iwo ko gbodo mira beni o ko gbodo soro nitoripe Emi mimo l'o nsise lara re yen**

**Ki a ma ba opo lo sile Oloro mo, oyun ni o tu asiri baba aladura pelu iyawo omo egbe-oro na wa tu s'epo, nigbati awon ijo pe, ti nwon se abere ise odale yi lowo Woli, e gbo bi**

**Woli tiwi:-**

O so wipe "e darijin mi, Esu ni o dan mi wo. Ise Esu ni, enyin, ara, e dariji mi"

A gbo wipe l'enu ... awon Jio egbe Kerubu ati Serafu na ... ninisivi, ko iti ni ...

Emi mimo sise lara iyawo omo egbe Serafu fun Woli o.

## Gomina Agba Pada De



SIR JAMES ROBERTSON

Gomina agba fun gbogbo Naijiria pada ti ilu Oyinbo de lojo Monday ti ise ojo kewa osu yi, o dakan lo ba oga Akowe Agba ti ilu Oyinbo, Ogbeni A. T. Lennox-Boyd soro ninu osc tokoja.

Awon ti o pade re ni ibudo oko Ofurufu ni Ikeja ni Alhaji Muhammadu Ribadu, Alabojuto ile, Ogbeni R. F. A. Grey, Akowe Agba, ati Oga'gun G. H. Inglis.

E k'abo o, Alafia k'ede Bi


## IWE IREPO OTITO

Iwe irepo Otito yi ni Aghara idide enia dudu nipa Ijoba Ominira.
Asa ati Esin ibile tiwa. O
KUN FUN OGBON ATI EKO.
O wa fun tita
3/-6d fun Eyokan, owo ifiranse si ldale 3d
36/- fun Meiila.
Lati Owo O OSONAIKE
14, Bridge Street, Lagos

# Irora Ibadi

Egbogi ti a se fun niyi.

Nigbati ibaradi ba ndun ni, eluwa re nfe itoju bi a ko ba tete fi egbogi re ko loju aisan yi a ma fa Ehin-didun, Lakuregbe, Wodi-wodi, Ako Esanri ati Igunfe-buruku wa.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio dari oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo le ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**

for Kidney and Bladder Troubles


## ENIA MỌKANLELỌGỌTA KU S'OMI LARIN OSU META

Irohin ti a gbo ni wipe larin osu meta pere, o di enia mokanlelogota to ku sinu odo ti a npe ni River Niger nitosi ilu Onitsha, ile awon Ibo.

Jamba ti o se gbehin ni ose tokoja niti oko Wete to ko enia metalelogun to s'ojude sinu omi niwon buso mewa si Onitsha, enia mejo ni o ku s'odo.

## Oko Arefo O Ra Abidjan

Ogbeni Tijani Atanda to ti ilu Abidjan dakaa wa ra oja nilu Eko ti pada lo si Abidjan ni Oke-Okun (Gold Coast ni ojo kejila osu yi. A fi eyi ki Ogbeni Tijani Atanda pe alafia ni o o de ohun o, ki o bawa ki Alhaji Salami Oyolola tiwa.

O Digbose.


# OVALTINE

JẸ ONJẸ MIMU TI O DARA JULỌ

O nmu ki enia ni ilera ti o ga julọ




"Ovaltine" nfun mi ni okun si ati agbara ti o jẹ pataki pupo fun gbogbo awon akẹkọ. O ntun ẹjẹ ṣe tobẹ, osi dun pẹlu — Nipataki bi enia ba nfi akara "Ovaltine" mu.

# Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
Medicine Store
7. Egerton Road, Lagos

**NOW AVAILABLE**

BUGLES. BEDSTEADS PAINTS DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just Write, Call, Or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**
20/28 Balogun Street. (P. O. Box 395) Lagos
AND
NEW COURT ROAD IBADAN

# Tribute For Late Orimo-lusi

BY S. O. SENJOBI

My relationship with the Orimolusi started from boyhood. Ever since neither of us had no cause to regret our connection. We



were both school mates and playmates and up till the time of his death, we did things together. His achievement in Ijebu-Igbo was most wonderful. His loss was regretted by the Ijebu as a whole and Ijebu-Igbo in particular. His office will be very hard to fill.

During the tenor of his office as an Oba, he has achieved so many things for Ijebu-Igbo.

It is a pitty that such a man did not live so long to reap the fruit of his labour, particularly now that Water and Electric lights have been earmarked for his town. Rediffusion, Hospitals, have his aim to achieve for Ijebu-Igbo and all purposes, independence, were burning in his mind until the end came at a time when no one expected it.

We pray for a real worthy successor.

## [illegible] 'ewon Najiria O Tun Wo Ti Gold Coast

Odomokunrin kan ti oruko re nje Edwin Ogunade to ti nse ewon ni Najiria ni o tun lo silu Aganyin ni

ero wipe awon ko ni mo on nibe nipa be on yio ri owo se.

Odomokunrin yi bere ise jibiti re, o ni on ni Alakoso Ile-owo Imesi (Manager Imesi Trading Company) ati Ile Ifowopamosi (Union Bank) ti owo bi adota egba a ponwun mbe nibe fun u.

Ki a ma fa gun, asiri tu.

## Ogbeni Oduyoye Ti Ilu Oyinbo De.

IBADAN. Ogbeni Osinlaja Oduyoye, alaga atijo fun Egbe awon Onisowo ti won nra ti won si nta sidale ni Ipinle Iwo Orun, (Western Region Association of Exporters and Importers) ese ti ilu Gesi de nibiti o ti lo wo ibi ipolowo awon oja ile Gesi ni osu karun odun yi, (British Industries Fair, May, 1955) lati igba na ti o ti ngbategun nilu Oyinbo.

Onisowo pataki ni ogbeni yi, o si se ise nla lati fi han awon Oyinbo nilu won pe onisowo atata po larin enia dudu, on na si tun fi kun ogbon ori re lona pupo.

Ogbeni Oduyoye je okan ninu awon ti nwon npolowo ninu "Eleti-Ofe" lati odun 1923, on lo si koko fi ero se buredi atata nilu Ibadan.

## Gomina Ipinle Iwo-Orun



SIR JOHN RANKINE

Qlola Gomina wa ni ipinle Iwo-Orun, ba oko Ofurufu de l'ojo Satide tokoja lati ilu re nibiti o ti gba olofe-ara lo. E ku abo o, Gomina tiwa.

# Jamba Efufu-Oji Sele Lapa Ilu Oyinbo

**London** A gbo irohin lati ilu Qba wipe, efufu oji lile kan se jamba buruku ni apa ona awon ilu Oyinbo lohun, tobe ti awon iya ati awon Baba Alanu ni lati dawo jo lati fi ran awon enia ti jamba sele si nwonyi lowo.

Awon eniti inkan yi soju re so wipe, lati iwon adota odun sehin a ko gbo tabi ki ari irufe oji lile bi eyi yi ri. Ategun buruku na bere lati ilu British Honduras; o fo ilu yi da, o bale sori gbogbo awon ileto ti o mbe lehin re, o so won di ile, gbogbo ilu kan ti a pe ni Korasal o baje kanle, o wo ile Alaisan, ile isin ilewe, ati awon ile ti o mbe larin ilu lo baje kanle-kanle.

Nigbati o gbera nibe, o bale sori ilu Barbados, o ba kanle iwon egbaa metela enia ni o so di asunta. Bi o ti kuro nihin, o kori si erekusu Grenada, jamba ti o se nihin tayo eyiti o ti nse lati ehin wa Gbogbo awon ile nlanla ti a fi Simenti, irin ati okuta ko lo so di ile.

Gbogbo awon ilu ti o mbe leti ebute ni o poora sinu odo, omi si kun bo gbogbo won mole ayafi awon ilu ti o mbe lona ile Oke. Gbogbo oko Koko, Agbon, Paki, ati awon ohun ogbin won fun odun yi, ni o baje patapata. Omi ti ko oko ogede lo

Odo ko san gba ona ibiti o ti ngba tele ri, Awo bi a ko ba ni se ete leso, ilu Grenada dabi ilu ti Ogun ja ti a si fi etu oloro (Bombs) baje, Nigbati gbagba-gbagbu na role tan agbara kaka ni a fi nri to enia mewa loju opopo.

Gbogbo awon ilu ti o mbe ni agbegbe ilu yi lo ngbaradi fun iranlowo awon ara Grenada. Awon egbe Red Cross ti St, John ti fi opo iranlowo ranse sibe, Amerika ko kere ninu iranlowo yi pelu,

Nilu Gesi, Ijoba ti da egba medogbon fun ilu Grenada ati Barbados, ati egbaa marun fun Honduras Jamaika da egba a marun, Trinidad egba medogun, Lowo jamba efufu lile, ti ina, ati ti omi, Oluwa fere gba wa,

Ki Olorun ma se jeki a ri iru re nile wa

## Irufe Ilu Wo Leyi?

OLOTU,

Jowo gba mi laye lati se ibere kekere yi lowo awon Okawe re, ki eniti o ba mo nipa re si laye mi

(a) Nibo ni ilu ti nwon npe ni Igbue wa?

(b) Bawo ni ilu na ti ri, ti awon Yoruba fi ma nfi pa owe bayi:- A ti ka Qba m, ki a to ka ara IGBUE?

Lati igba ewe mi ni mo ti ma ngbo oro yi lenu awon baba wa, ko si ye mi titi di oni, e jowo eniti o ba mo, ki o fi yemi ninu Iwe Irohin Eleti-Ofe.

Mo dupe o, Emi ni,

G. A. Folorunso.

WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

VACANCY FOR ACCOUNTING ASSISTANT.

Applications are invited from suitably qualified candidates for a vacant post of an Accounting Assistant.

Salary will be in the scales £414x24-486; £510x30-690, point of entry depending on qualifications and experience.

Application in the applicant's own hand-writing together with full details of experience and qualifications should be submitted to reach:

The Personnel Secretary,
Western Region Production
Development Board,
Ibadan,

not later than 17th October, 1955. Only applications of those selected for test and interview will be acknowledged.

## Yokolu, Iyawo Gbe Oko Sanle, Oko Yo Ike

(O bere ni oju kerin)

Bi o ti de oja Alagbado ti o nwa iyawo rẹ kiri beni o kofiri iyawo re nibiti on pelu omokunrin kan gbe mba ara won ta. Inu Taiwo baje, o so fun pe omo re oke nile. Lese kanna Kehi de pada sile, yamo-yamo, oko re ti lo le gongo de nile. Gere ti o wole, beni Taiwo oko re fa atori yo o ko bo o, Kehinde sare jade nile, gbogbo ara Agbesi lo mu Taiwo ti o wipe ayafi bi on ba paa.

Nigbati ko gbọ Iyawo sa jade lo si Olomo lodo ẹgbon rẹ obinrin, Taiwo ọkọ re tun lepa re. Nibia ni Kehinde se lle re pe on ko nisa fun mọ. Bi Taiwo ti de ti o foju kan Kehinde Iyawo re o pakuru mo, Iyawo re, si di igbaju ru oko re beni oju Taiwo kan ba fọ bamu-bamu. Ko ha tan bi, iyawo gbọko ṣanle oko, yoke, yọkolu, yọkọlu.

## Ope Ba Akuko J'aporogan, Akuko Bo'le Bamubamu

Ohun ti oju ri ninu oro to so, enyin ara wa. Awon t'egbon-t'aburo kan wa ti nwon je omo baba ati iya kanna, enia soro daruko, bi beko, a ba daruko won fun enyin okawe wa.

Egbon nse egbe Alakuko (N.C.N.C.) aburo nse egbe Qlope (Afenifere tabi A. G.), nigbati egbon je kumoyo tan, o pe aburo re, o so fun wipe lati oni lo, on ko ni sunmo ohunkohun to ba f'ara jo Qpe mo, aburo si wi fun pe ohunkohun to ba f'ara jo Akuko, on na koni sunmo sakani re mo.

Ki a ma fa oro yi gun, awon mejeji ke si awon alagba ki nwon o ba awon se eto ibura, ki awon bura, le adehun awon na l'ori. Awon alagba enia ko fun won wipe ona ko si nibe, eda alaye kan ko le ri ona ba wo o nile aiye yi, laiko ni ba Qpe se. Egbon ko, o fi ake k'ori, o wipe ki nwon sa se eto ibura fun awon ki awon bura.

Se enyin na mo wipe "Aja to ba ma sonu, ko ni gbo fere ode" a fi igbati nwon je ki awon tegbon t'aburo na, bura ni o to te egbon lorun.

Lehin ti awon mejeji bura tan, egbon pe iyawo re, o so fun wipe lati oni yi lo, ohunkohun to ba jemo Qpe, onko fe mo nitorina, on ko fe epo isebe mo iyawo ni o dara, on gbo, nje ki o mu owo wa ki on lo si oja lo ra onje egbon mu sile kan fun u, iyawo re fi Qpe han l'ara owo sile kan,

O dahun, o ni eyiti a o se ku. o so wipe on na yio ba iyawo lo si oja laiko ni mu owo dani, on yio si ri oja ra l'awin, nitoripe enia mimo mbe fun on l'oja, o so eyi lehinti o ye Iwe owo

(Wo oju ewe kejo)

## TEMBELEKUN BE SILE NILU EPE

**Epe** Awon Egbe Afenifere (Action Group) to wa nilu Epe pin si meji awon apakan nje Parapo, awon apa keji nje Faramora, awon Ijo mejeji yi egbe Afenifere ni won. (Action Group)

Nigbati nwon se idibo yan awon enia sinu Ajo Igbimo Ibile ti ilu Epe, awon Ijo Ijebu Parapo fi eyo meji pere tayo ti awon Ijebu Faramora, nipa ille ti enia Ijo Parapo le yi mu ki nwon tubo mura si ete ati ero won wipe ollu Epe Ijebu nikan ni yio ma soro nibe.

Awon Ijo Faramora je yiti Olola S.L Edu nse Alakoso re, Olu-Epe si ni Baba egbe fun Ijo Faramora na. Awon Ijo Ijebu Parapo ni eyiti Olola O. Tobun je Alakoso re, awon ni nwon nfe se ise Asoju, "Anikan gbe'ju ilu Epe.

### AKO F'OKAN TAN AN MO

Ninu ipade gbogbogbo ti Ijo Faramora pe ni Epe ti Oloye Shittu Balogun, Eleilorin ti ilu Ejinrin se Alaga, ni gbogbo awon omo ego enia to wa si ipade ti se ipinnu wipe awon kofi okan tan Ogbeni O'ayemi Tobun mo nipa iwa tembelekun a'i idaru-dapo re larin awon ara Epe.

Awon ilu to peju-pesi sibi ipade nla yi ni Epe, Eredo, Lekki, Ikosi, Imota, Ejinrin ati Ibeju.

## High Court Of Justice Western Region Of Nigeria.

It is hereby notified for general information that, as from this date, Civil Summonses and all other civil processes intended for ABEOKUTA JUDICIAL DIVISION will be filed at the following places:-

| | |
|---|---|
| From Abeokuta and Ijebu Provinces | — High Court Registry ISABO, ABEOKUTA. |
| From the Colony Province | — Magisrate' Court, Ikoja. |

Dated at the High Court of Justice, Ibadan the 7th day of October, 1955.

N, C, A. MORGAN

Acting Chief Registrar.

*Only Shell's patented I.C.A. gives you ALL the power of the NEW higher octane motor spirit*

The most powerful motor spirit you can buy

SHELL

WITH

ICA

IGNITION CONTROL ADDITIVE

*Fill up and FEEL THE DIFFERENCE*

# Kungu To L'ebute Ehingbeti

I'owuro ojo Jimo (Friday) ose yi ni iran dun wo l'bute Ehingbeti nigbati awon osise Munisipa lo ba awon Qde Apeja ti o ma fi oko-ode won gunle si Ebute Ehingbeti l'okakan ile Afin Ogun.

A ni oro wipe awon Munisipa ti se ikilo fun awon Qde Areja enia wony pe ki nwon mase fi Oko-ode won gunle si Ibute na mo nitoripe bi awon ode ti fi oju kan awon osise Munisipa na ni nwon ti fu gbogbo oko won, ti nwon si wa won si arin agbami. Oro na wa di "O ke re, eniba mo'we k'o bosi" fun awon Osise Munisipa.

Awon osise Munisipa ko le wo odo, awon ode ko si fi oko gunle, o wa di wom awo o, fun awon mejeji. Ki e wo bi gbogbo ati Ebute ti atu yeri-yeri fun opo ero iworan.

## Adura Fun Ose Yi

Gbawa Olowa, lowo jamba Osan ati T'oru, ki o si fun wa ni okun-ara ati emi irele, ki awa ki o le ma a tele ilana re. Amin.

# PUBLIC NOTICE

## H. M. S. "SPARROW" To Visit Lagos.

H. M. S. a "Sparrow" flying the Flag of the Commander-in-Chief, South Atlantic, Station, Vice-Admiral I. M. R. Campbell, K. B. E., C. B., D. S. O., will visit Lagos from Thursday 27 October to Wednesday 2 November.

H. M. S. Sparrow is a Frigate and has a complement of 11 officers and 180 men.

A programme of sports, visits to places of interest and general entertainment is being arranged.

On visits such as this, offers of private hospitality for the ship's company especially the ratings are welcome. Persons wishing to offer such hospitality should make contact with the District Officer, Lagos, at the Office of the Chief Administrative Officer, Broad Street, Lagos.


# Aradan Nervigora

Ogun ti o pataki fun imarale agba ati aremo pipe fun awon alaya pupo. O da a fun inarun, oju dudu, sokun oju, gbigbon owo, ailesun, ailokun nnu, ati iru fe arun bi wonni o je ajidewe fun awon ti agbara won ndinku. On na gan ni okunrin yi lo ti o fi di "Afise kun bi ojo" 5/-6d pere ni pelu owo oko 1/-6d. e. g. 7/-Post Free.




## The Egba Trading Aradan Stores

144, Denton Street, 18, Denton Bridge Street
P. O. Box. 2. Ebute Metta Phone 44153
ati wa ni New Motor Park (Ogunpa Ibadan


## Njemanze Di Ige Adubi

(O Bere L'oju Ewe Kini)

ko pania, nko ni nkankan pelu ologbe na nko si pa a.

Samuel Jegede wipe ki nto so ohunkohun, Qlorun to da gbogbo wa mope mo feran ologbe na, mo tile ma nya lowo, nko si ni ibinu kan si i.

ODARAN



SAMUEL JEGEDE

Lehinna ni Adajo sa konko le won l'ori, o si so fun won wipe aye wa fun won lati gbe ejo won si Kotu Kotemilorun larin ojo medogun.

## Ikilo Nipa Oye Oba Orimolusi Ti Ijebu - Igbo.

Nipa awon oro ti nwon te jade ninu Iwe Irohin ojojumo, Daily Times ati Daily Service ti ojo karun ati ojo kefa osu yi lori aye ipo Oba Orimolusi ti Ijebu-Igbo to si sile, ni awon Igbimo alasaro ti Egbe Omo Ijebu-Igbo (Ijebu Igbo Patriotic Society) fi se ikilo yi fun enikeni to ba je omo Ijebu-Igbo, ti o si ni ife ati ire ilu na l'okan wipe ki o dawo a nko ohunkohun sinu Iwe Irohin duro nipa eniti yio ro'po oye Oba Orimolusi.

Fun etigbo gbogbo enia, awon Igbimo Ibile ti Ijebu-Igbo ti fi oro yiyan enia si ipo Oba na le Igbimo awon Ijoye ati awon Af'obaje lowo, awon ni eniti o ni eto lati se eto na, nitorina, ki enikeni ti o ba ni ife ilu Ijebu-Igbo mase se ohunkohun ti yio ma mu royi-royi si won l'okan, l'ori ise pataki ti nwon ti fi le won lowo yi.

O ye ki enikeni ti o ba ni ife ilu wa, ki o ma gbadura wipe, ki Olorun Olodumare massi yan enia ti o to fun asiko yi fun wa, ki o si so oke isoro wa di petele fun wa.

F. Ade. Adesanya,
Akowe Egbe

# Omikun Wo'nu Ile Nilu Ibini

BENIN— Opolopo ile ni Omi kun wo inu won nilu Ibini ati Obaje ti ise Ilewe Ibile ni omi kun wo inu re.

Won so wipe ojo to ro ni odun yi po pupoju tio fi je wipe iru re ti ro gbebin ni opolopo odun lori.

Opopo ona Ibini si Sapele ni okokan Ologbo ko se gba koja fun omi to kun na.

## Ope Ba Akuko J'aporogan, Akuko Bo'le Bamubamu

(O bere l'oju ewe keje)

wo (Currency Not) ti o fun ri ope lara re bakanna.

Nigbati nwon de oja, nwon lo si Iso awon eleja, won ba Igbale lowo awon eleja ti nwon fi n e Esinsin, bakanna ni Iso awon eleran, o pe Iyawo re o ni ere gbogbo di ile, nwon pada wa'le laiko le ra nkankan bo. Nigbati nwon de ile, egbon ko fi oro bo epo, bo iyo, o pe aburo re, o si tun ke si awon alagba enia, o wipe on gba daju-daju wipe bi enia ba ko lati ba Ope se, oluware ko ni gbe ile aiye.

Nitorina, awon yio se etutu lati re ibura won, o si se inawo etutu na, o si so ile re ati ona re di egbe Qlope (Afenifere - Action Group) o yowo-yose re kuro ninu egbe Alakuko.

Eyi fi han wa gedegbe wipe ko si eniti o le ko ti Ope l'aye wa yi, nitorina, bi asiko ba to lati dibo, ki a ma gbagbe lati dibo fun Qpe igi-owo.

EDIBO FUN OPE, ENITI KO BA DIBO FUN QPE KO S'ORIRE.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370